# ROGBODIYAN ILU OYO TI BI IGE O BI ADUBI


**Just Arrived**

**Rubber Sheetings**

ITẸ OMODE
MARMITE 2 ozs
" 4 "
ALAFIA BITTER
Thompson's Blood Tonic
To Clear at reasonable Prices
Call at

**Alafia Medicine Stores**

16, Idumagbo Avenue, Lagos,



# ELETI OFE

A-NJU-WON KO SE WI-EJO



NOW AVAILABLE

BUGLES, BEDSTEAD, PAINTS DISTEMPERS, SAFES Etc.
Just write, Call, or Phone 21372

**IKORODU TRADING COMPANY**

20/28, Balogun Street,
(P.O. Box 395) Lagos,
AND
NEW COURT ROAD
IBADAN



VOL. VII No. 336 LAGOS (SATURDAY) ỌJỌ ABAMẸTA NOVEMBER 7, 1953, IYE OWO ELETI ỌFE KOBỌ MEJI (2)


## Ilgan Be Larin Awon Omo Suenu

**Eko** Ede koyede kan ti mbẹ larin awon ọmọ Oloye Suenu ti ko jẹki awọn ẹbi Oloye panupọ fi yan ẹnikan soṭi oye baba wọn ti o ti ku ni nkan bi ogoji ọdun sẹhin.

Ọgbẹni A.K. Suẹnu li o pe Wahabi Layinka lẹjọ si kotu wipe on gegbi ẹniti Oye Suẹnu kan nfẹ ki Layinka da gbogbo dukia Oloye Suẹnu pada fun on ẹjọ na si wa ni kotu nisisiyi di ọdun keje.

Adajọ da A.K. Suẹnu lare, o si paṣẹ wipe ki Layinka ko lọ san Poun mejilelaḍọta ati sile mẹwa owo irin ọṣẹ fun Suẹnu ki o si lọ ko gbogbo Dukia ti a fi nlẹ oye na silẹ kiakia.

Nigbati nwọn jade kuro ni Kotu awọn alatilẹhin fun awọn elẹjọ meji ri wọ iya ija. Awa *Eleti* ki Oloye Suẹnu ku *ẹtiro* oye a mọri o.




## Awon Ti O Fi Ara Korin Ninu Egbe N.C.N.C.

**London** Ọkan ninu awọn oyinbo igbimọ ilu Ọba lo bere lọwọ Sekiteri agba ni ilu Oyinbo wipe on gbọ pe iwa aidara po larin awọn igbimọ Nigeria, ki Sekiteri na fi ye wa, awọn wo ni a ba se ẹjọ larapa iwa buruku yi Sekitẹri agba si dahun bayi wipe.

Nilẹ Ibo

M.W. Ubani. O la jibiti ẹjọ rẹ si wa ni kotu.

M.E. Ogon, o ba awọn ọlọpa fajọgbọn, ẹwọn oṣu mẹta sugbọn o gba ẹjọ lọ si Appeal.

D.C. Ugu Ojale ẹwọn oṣu mẹsan.

E.U. Eronini O jale bakanna, ẹwọn oṣu mẹsan sugbọn o nlọ si appeal

Dọkita Orisu O jale ẹwọn ọdun meje

S.J Una O wa mọto sare ju ko le san adọta poun

N.Nwaese O ko ẹru sinu Reluwe lai gba iwe ki o lọ san pọun mọ́ adilogun

A. Adedoyin O ko awọn enia sẹhin laigba iwe aṣẹ ki o lọ san adọta poun,

## Rogbodiyan Ilu Oyo Kuro Ni Kekere

**Eko** Bi owu ẹ̀ ko to nkan tobẹ ko to, nkan fila imalo ku pere ki, rogbodiyan kan ti o bẹ silẹ nilu Ọyọ laipẹ yi jẹ eyiti awọn ara Eko nfi oju yẹpẹrẹ wo, sugbọn ọrọ na ti bi Ige o si ti bi Adubi nisisiyi nitoripe awọn igbimọ Ibile Ọyọ ati awọn *Oloye* lu fi fi ake kọri wipe dandan awọn ko ni fẹ Alafin mọ ni ọba.

Awọn ti o jẹ alatilẹhin fun Alafin paapa taku wipe ka i kuti ni ọrọ yẹn awọn ko si gbodọ gbọ mọ. Eyi li ohun ti o mu awọn igbimọ ijọba-ibile ati Gomina Ibadan ti awọn fi ti de si ọrọ na.

Nisisiyi o dabi ẹni wipe ja ba nfẹ mu epo nitoripe Alafin ti bẹrẹ si jirebẹ wipe on ti tẹramọ ohun ti awọn ijoye nfẹ, on ko si ni da si ọrọ owo ori mọ bẹni on ko ni lo ida on mọ. On ko ni ba ẹnikẹni mọ. Ohun kohun ti awọn afọbaje ba nfẹ, on yio fi ara mọ, ati pe awọn ọba ni ki nki ọ gbogbo on yio da wọn duro.

## E 'Kagilwe Eleti Ofe



## Iwa Aibikita Koye Qmo Enia Rara

Lati ọwọ D. O. Ọdẹfin

Nigba lai'ni ọrẹ meji kan wa ti wọn fẹran ara wọn, ọkan ja ọmọ ola o si ni owo pupọ, ekeji jẹ akuṣẹ awọn mejeji jumọ njẹun, Nile ẹl.rọ yi si ni ọrẹ akuṣẹ na ti njẹun.

Ni ọjọ kan olowo yi ronu pupọ lati da ọrẹ rẹ akuṣẹ yi li ọla, o lọ si inu ọgba o lọ ja elegede kan o si fi ọbẹ ge ni ẹgbẹ ti o fi jẹ pe o ti aye ko gbogbo pọn-tiri inu rẹ danu o ko owo kun inu rẹ o wa pade ẹnikeni ko si le mọ rara pe owo wa ninu rẹ.

Nigbati ọrẹ akuṣẹ yi de lati wa jẹun ọsan lọdọ ọrẹ rẹ. Olowo yi gbe elegede na fun lẹhin ti o jẹun tan o wipe ki o lọ fi se ọbẹ jẹ. Lẹhin ti ọrẹ akuṣẹ yi kuro lọdọ ọrẹ rẹ ti o n'ọ sile ni o pade iyagba kan li ona ti o tọrọ elegede yi, Ọkunrin yi si gbe fun iya arugbo na.

Nigbati osi tun to bi iwọn osu mẹta ti ọrẹ yi ti gbe elegede na fun o bere pe njẹ iwọ ha jẹ elegede ljọsi? Ọrẹ rẹ si dahun pe on kojẹ ẹ nṣe ni o fi tọrẹ, ọrẹ yi tun ṣe bẹ nigbakeji otungbe fun ki a ma fa gunlẹ titi Iya yi tun pade rẹ lọna o tun tọrọ elegede na, ọkunrin yi si tungbe fun.

Nigbati o matun to osu mẹta si ọrẹ rẹ yi tun ṣe bẹ ni ori ẹlẹkẹta ni oto ọfun pe ki o maṣalai jẹ elegede na pe o dun pupọ osi gbe fun. bẹ I o tun pade iya yi lọna iya yi si tun tọrọ rẹ nigbati iya ma tọrọ rẹ ni o sọ fun Iya pe on papa fẹ lọ o.

Nigbati ọrẹ yi dele, o ojoko, o mu ọbẹ fi ge elegede yi ni owo ba tu jade Ha! ti ọkunrin yi laṣu pe nu nkan bayi ni on fi nṣẹrẹ ko le pa ẹnu ayọ de mọ lọọko, ki Olọdumare maṣe jẹki Irẹ ile aiye tase wa o, nipa Iwa aibikita ni ọkunrin yi fi sọ orire rẹ nu.

## Salami Ayeye Di Ologbe

**Ibadan** Bi ẹda enia ba ọpere Olọrun a si ma pete tirẹ. Salami Ayẹyẹ ni awọn oyinbo fẹ ki o joye Olubadan li aṣeko kan alleyi Ṣugbọn ohun ti o ṣe idi lọwọ ti ko jẹki ukan na ṣeṣe ni wipe nigbani, Salami koi ti jẹ oye ti o le gbe de ipo Olubadan.

Ohun ti o jẹ ki o fi ri bẹ ni wipe, Salami Ayẹyẹ mọ iwe, o si gbọ ede oyinbo, tobẹ ti awọn fi yan a si igbimọ aṣofin fun agbegbe ilẹ Ọyọ li ọpọlọpọ ọdun sẹhin.

Ṣugbọn nkan ṣe ni jọọ lati gbe ire Salami Ayẹyẹ na, nigbati o jẹ wipe bi Olubadan ba ku, Ayẹyẹ ni yio joye gẹgẹbi ibere ti awọn awọn ara Ibadan ma nibere nṣe yi Ayẹyẹ ko joye Olubadan mọ, otun Balogun ni yio tun pada jẹ oye Olubadan.

Ọgẹ i ṣṣa ọtin awọn ara Eko, awọn wipe, ọ ko ri bayẹ ti nlọ ta'i ẹ ko ti gori ọ ọjọ ọrọ ni o,

## E Ka Iwe Ẹleti Ọfe

## Ikede

Iwe irohin Ẹleti Ọfẹ ti di ohun ti gbogbo ilu nkọwe bere fun nisisiyi tobẹ ti o fi jẹ wipe ẹgbẹrun mẹta ti a ntẹjade ni ọsẹ ko nto fun pinpin, bẹni a ko si ri awọn ohun ela ti fi nlẹ iwe na ra deedee.

Nitori idi eyi, a fẹ lati fi ye awọn Ọkawe wa nile, li Oke Ọyọ, ati si Oke Okun wipe ẹnikẹni ti ko ba san owo Iwe irohin tirẹ ko ni ri iwe ra mọ. Nitoripe bi a ba ri o y ka mọ ohun ti a fi aru jẹ.

OLOTU

## Awon Ara Awe Faramo Balogun Oyo

**Awe** Gbogbo awọn ara ilu Awẹ ṣe ipade kan ni Awẹ ninu eyiti gbogbo wọn fohun ṣọkan lati jẹ alatilẹhin fun Bọde Thomas ti o nṣe Balogun Ọyọ ati, awọn ẹgbẹ Afẹnifẹre, Balẹ Awẹ wa ninu ipade na, ati awọn Ijoye ilu Awẹ lo fara mọ eto ẹgbẹ na.

Gbogbo wọn lo sọ wipe awọn gbagbọ wipe ẹgbẹ Action Group nwa ilọsiwaju ilẹ Yoruba, lati kọ ni li ẹkọ ọfẹ, nipa ẹgbẹ yi a ni-e reti pe, ọpọlọpọ anfani ni a ri nibẹ nilẹ Yoruba.

## Awon Ebi Eniti O Ku Ni Kano Yio Gbowo

**Kano** Irohin kan wa wipe awọn Igbimọ ti a yan lori iye owo ti o yẹ ki a fi fun ebi awọn ti o ku ninu ijagboro ti o ṣẹlẹ ni Kano ti bẹrẹ si ṣe eto wọn awọn o si pari rẹ ninu oṣu Nov. 11th 1953 Lẹhin na ni awọn o wa sọ iyẹ ti awọn o fun ẹnikọkan ti ku ninu ajigbero na.



